# IṢỌTẸ ISRAẸLI SI ỌLỌRUN

## Numeri 14:1-45

## ẸKỌ 102 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Nipasẹ Ọlọrun li awa o ṣe aki: nitori on ni yio tẹ̀ awọn ọta wa mọlẹ" (Orin Dafidi 60:12).**

### Oju Wọn Ṣí Kuro Lara Oluwa

Awọn Ọmọ Israẹli ti de bebe Ilẹ Kenaani gan an, wọn si ti jẹ ki irẹwẹsi mu wọn kuna lati gbadun ibukun ti o wa nibẹ. Lẹyin ti wọn ti fi ẹsẹ̀ rin pẹlu gbogbo agbo ẹran ati maluu wọn, ati awọn ọmọ wẹẹrẹ wọn fun akoko ti o lé ni ọdún kan, wọn i ba ti gba ilẹ daradara naa nisisiyii pẹlu ọpọlọpọ eso ati wara ati oyin rẹ̀. Ṣugbọn wọn ṣí oju wọn kuro lara Oluwa, wọn kò si le ri ibukun naa.

Ko si bi a ṣe le sin Ọlọrun tọkantọkan to fun igba diẹ, bi a ba ṣí oju wa kuro lara Jesu, bi a ba kuna lati gbadura ati lati ka Ọrọ Rẹ̀, ki a ba le mọ ohun ti O fẹ ki a ṣe, a ki yoo de Ọrun. Jesu lọ si Ọrun lati pese àye silẹ fun awọn ti wọn fẹ Ẹ, ayọ̀ ti a o si ni nigba ti a ba de ọhun ju ohun ti a le fi oju inu wò nisisiyii. Ṣugbọn bi o tilẹ jẹ pe a ti fẹrẹ de ẹnu ilẹkun Ọrun, lẹyin naa bi a ba jẹ ki ẹṣẹ yọ́ wọ inu igbesi-ayé wa, a ki yoo wọle lati gbadun ibukun ti a ti pese silẹ fun wa.

### Titan Ihin Buburu Kálẹ̀

Awọn amí ti wọn ti rí gbogbo ohun rere ti o wà ni Ilẹ Kenaani bẹru awọn eniyan ti n gbé ibẹ̀, wọn si tan ẹrù kalẹ yikaakiri ibudo awọn Ọmọ Israẹli. Inu bi Ọlọrun si awọn amí wọnyii to bẹẹ ti O rán ajakalẹ-arun ti o pa gbogbo wọn patapata, Ṣugbọn nnkan ti bajẹ ná. Oró majele aini itẹlọrun ati aigbọran wọn si aṣẹ Ọlọrun ti tàn kalẹ kaakiri laaarin awọn Ọmọ Israẹli nisisiyii. Awọn eniyan wọnyii sọkun nitori wọn bẹru awọn omirán naa. Awọn alagbara ọkunrin Israẹli di ojo to bẹẹ ti wọn fi n sọkun! Ro o wò bi abayọrisi iroyin buburu lati ẹnu awọn ọkunrin amí mẹwaa wọnyii ti buru tó. Ẹru ba ogun nla Israẹli.

Nitori ibẹru wọn naa, a dá awọn Ọmọ Israẹli pada sinu aginju lati tun maa rin arinkiri fun ọdun mọkandinlogoji (39) si i, wọn ko si jẹ igbadun Ilẹ Kenaani mọ́. Ilẹ daradara yii ti n bẹ ni arọwọto wọn gan an, si bọ́ sọnu lọwọ wọn laelae. Awọn ọmọ wẹẹrẹ wọn, ti wọn sọ pe yoo kú ninu aginju, ni wọn jogun ilẹ naa nikẹyin.

Bawo ni o ti dara to lati ṣọra gidigidi ki a ma ṣe mu irẹwẹsi ba ẹnikẹni ninu awọn ọmọ Ọlọrun! Ọrọ diẹ ti a ba sọ laironu le mu ki igbagbọ ẹlomiran di alailagbara; njẹ ko ha ni buru pupọ ju bi a ba mu ẹni kan padanu Ọrun?

### Òmirán ati Ẹlẹnga

Njẹ awọn omiran Ilẹ Kenaani ba ni lẹru to bẹẹ? Kalẹbu ati Joṣua kò ro bẹẹ. Awọn naa pẹlu jẹ́ amí, wọn ti rin ilu naa já, wọn si ti ri gbogbo nnkan ti awọn amí mẹwaa iyoku rí. Ṣugbọn oju miiran ni wọn fi wò ó. Wọn ni oju igbagbọ, wọn si mọ pe Ọlọrun yoo ṣẹgun fun wọn. Wọn gba Ọlọrun gbọ́; wọn si wi pe, "Awa le" gba ilẹ naa. Wọn wi pe aabo ti kuro lori awọn ara Kenaani, "onjẹ wa ni nwọn."

### Ọgbọn Joṣua

Joṣua ni balogun awọn Ọmọ Israẹli, o si jẹ oloootọ ati ọlọgbọn eniyan to bẹẹ ti a fi yan an lẹyin naa lati mu awọn eniyan naa kọja Jordani. Bi o ba jẹ pe lootọ ni ewu wà, njẹ iwọ kò ro pe o yẹ ki o ti mọ̀? A mọ pe Joṣua ati Kalẹbu mọ ibi ti agbara wọn wa, nitori wọn wi pe: "Ṣugbọn ẹ máṣe ṣọ̀tẹ si OLUWA, bẽni ki ẹ máṣe bèru awọn enia ilẹ na; …OLUWA si wà pẹlu wa" Wọn mọ pe bi Oluwa bá wà niha ti wọn, wọn yoo bori ogunkogun. Ṣugbọn awọn eniyan wọnyii ko feti si awọn amí ti wọn mú ihin rere wá. A ti mu wọn rẹwẹsi, ero buburu nikan ṣoṣo ni wọn si le rò.

### Ọtẹ

Ọlọrun ti mú suuru pupọ fun awọn alaigbọran eniyan wọnyii nitori Mose gbadura fun wọn. Ọlọrun ti fun wọn ni ounjẹ lati jẹ; aṣọ wọn kò gbó; awọn ọta wọn si ti ṣubu niwaju wọn. Wọn ni eredi pupọ pẹlu lati gbagbọ pe Ọlọrun yoo ja ogun yii. Ṣugbọn dipo eyi, wọn gbagbe awọn iṣẹ iyanu ti o mú wọn jade lati Egipti, ti o si mu wọn wà laaye titi di ọjọ naa, wọn si kigbe soke; "Awa iba kuku ti kú ni ilẹ Egipti! tabi awa iba kú li aginju yi!" Njẹ iwọ le fi oju inu wo iru iwa aimoore bayii? Wọn si tun ṣe aibu ọla lọpọlọpọ fun Ọlọrun ati Mose nipa sisọ pe, "Ẹ jẹ ki a yàn olori ki a si pada lọ si Egipti." Wọn fẹ aṣaaju miiran ẹni ti yoo mu wọn pada si ilu buburu Egipti.

### Egipti, Apẹẹrẹ Ẹṣẹ

A kọ́ ẹkọ pe, Egipti jẹ apẹẹrẹ ẹ̀ṣẹ, Ọlọrun si ti mu awọn eniyan Rẹ̀ jade kuro ninu rẹ̀. Irẹwẹsi ti de nisisiyii, wọn n fẹ pada lọ sibẹ. Ṣugbọn ki ni wọn fẹ pada lọ bá? Ẹrú Farao ni wọn ti jẹ́ rí, wọn si ti ṣiṣẹ lile lọpọlọpọ labẹ ilagbà awọn akoniṣiṣẹ. Wọn ti kigbe pe Oluwa ninu ìṣẹ́ wọn, Oun si ti da wọn silẹ. Ki ni i ba jẹ opin wọn bi o ba ṣe pe wọn

ti pada?  Lai si aniani ọba ti inu n bi yii i ba ti jẹ wọn niya gidigidi fun sisá ti wọn ti sá lọ, o si daju pe oun i ba ti mu ẹrù wọn wuwo si i lọpọlọpọ.  Ṣugbọn Israẹli ko duro lati ronu nipa eyi.

Bẹẹ gan an ni opin ọkunrin naa ti o kọ ire ije Onigbagbọ silẹ, ti o si pada sinu ẹṣẹ.  Eṣu jẹ akoniṣiṣẹ ti o le, oun yoo si di ẹru ti o wuwo le ẹlẹṣẹ naa lori.  Lẹyin eyi paapaa, iyà ainipẹkun n duro de afasẹyin naa, bi kò bá tun ronupiwada. Ni akoko irẹwẹsi, eniyan le di alailagbara, ki o si rò pé oun ko le di igbagbọ oun mu ṣinṣin mọ́; ṣugbọn ni iru akoko bẹẹ o gbọdọ sinmi le Oluwa patapata fun agbara, ki o si mọ pe opin ti o buru ju eyi lọ n duro de oun bi oun ba jọgọ silẹ ninu ire ije Onigbagbọ.

Ọlọrun i ba ti pa awọn Ọmọ Israẹli run fun ọtẹ yii, bi ko ba ṣe pe Mose ati Aarọni tun gbadura kikankikan fun wọn.  Wọn sọ fun Ọlọrun pe gbogbo awọn orilẹ-ede ti o yi wọn ká ni wọn n ṣọ́ irin-ajo awọn Ọmọ Israẹli, wọn si mọ pe ọmọ Ọlọrun ni awọn wọnyii i ṣe.  Bi O ba pa wọn run nisisiyii, awọn Keferi yoo sọ pe Ọlọrun otitọ ko lagbara ju awọn ọlọrun ti wọn n sin lọ, ati pe Oun ko lagbara lati mu wọn lọ si ilẹ ti O ti ṣeleri.  Ọlọrun feti si ẹbẹ Mose ati Aarọni, O si ṣeleri pe aanu yoo dapọ mọ idajọ ti Oun yoo rán.  O jẹ oloootọ si ọrọ Rẹ pe wọn ko le wọ Kenaani, ṣugbọn Oun yoo fun wọn ni ogoji ọdun lati ronupiwada.

Laaarin ọdun pupọ wọnni ti awọn Ọmọ Israẹli fi n rin arinkiri ninu aginju, aye ṣí silẹ fun wọn lọpọlọpọ lati kaanu pe wọn ko gba Ọlọrun gbọ́.  Nigba ti wọn wa ninu wahala nlá nlà, wọn yoo maa da ara wọn lẹbi.  Ẹṣẹ wọn ni o mu gbogbo wahala yii ba wọn.  Wọn n fara da gbogbo iya wọnyii nitori wọn ko gba Ọrọ Ọlọrun gbọ́.  Wọn ko gba Oluwa gbọ nigba ti O wi pe Oun yoo maa lọ niwaju wọn, Oun yoo si ba wọn ja ogun wọn.

Paulu Apọsteli sọ fun wa ninu Heberu ori kẹta pe, wọn ko jogun Ilẹ Ileri naa nitori aigbagbọ.  Awọn eniyan lonii ko ro pe ẹṣẹ ni lati ṣe aigba Ọlọrun gbọ.  Awọn Onigbagbọ miiran paapaa ko ro pe o lewu pupọ bi wọn ko ba gba eyikeyi ninu ileri Ọlọrun gbọ́.  Ṣugbọn o lewu lati ṣe aigba Ọlọrun gbọ.  Bi awọn Ọmọ Israẹli ba kuna lati wọ Ilẹ Kenaani nitori aigbagbọ, awa pẹlu le padanu Ọrun nitori ẹṣẹ ti ko ju eyi naa lọ pe a ṣiyemeji apa kan Ọrọ Ọlọrun.

Bi awọn eniyan ba gbagbọ ni tootọ pe iya ainipẹkun ninu ọrun apaadi ti ina n jo n duro de wọn bi wọn ba ṣaigbọran si Ọlọrun, njẹ o ro pe awọn ẹlẹṣẹ pupọ bayii yoo wà?  Ọpọlọpọ awọn eniyan ti ki i ṣe Onigbagbọ ni wọn ko tilẹ gba Bibeli gbọ rara; ṣugbọn awọn miiran ti wọn jẹwọ pe awọn gba a gbọ, n ṣiyemeji pe njẹ lootọ ni ọrun apaadi jẹ́ ohun ti Bibeli sọ pe o jẹ́.  Wọn nireti pe lẹyin ti wọn ba kú tan, ọna abayọ miiran le wa, tabi boya ọrun apaadi ko buru to bi a ti ro o si.  Iṣẹ Eṣu ni lati yi ero awọn eniyan pada nipa idajọ Ọlọrun titi yoo fi pẹ ju lati ronupiwada.  Akoko kan n bọ fun olukuluku eniyan nigba ti ko ni si aanu fun wọn mọ, bi o ti wu ki wọn gbiyanju pupọ to lati bọ́ lọwọ ijiya.

**Awọn Ọmọ Israẹli Yi Ọkàn Pada**

Lẹyin ti Mose sọ idajọ Ọlọrun fun awọn Ọmọ Israẹli, ẹru ati tun rin kaakiri ninu aginju fun ọdun mọkandinlogoji si i ba wọn to bẹẹ ti wọn fi pinnu lati lọ ba awọn ara Kenaani jagun.  Ṣugbọn a ti ṣe idajọ wọn ná, a si ti pari rẹ̀.  Idajọ Ọlọrun ti wá sori wọn, ifarahan Rẹ si ti kuro laaarin wọn.  Ko ṣanfaani fun wọn nisisiyii lati gbiyanju lati ṣẹgun awọn ọta ninu agbara ti wọn.  Iru opin wo ni yii!  Ọlọrun ti kuro laaarin wọn!

Mose ṣipẹ fun awọn Ọmọ Israẹli pe ki wọn má ṣe huwa omugọ to bẹẹ ti wọn yoo fi gbiyanju lati jà ninu agbara ti wọn, ṣugbọn wọn ko ṣe e dá duro ninu ikugbu wọn yii lati jade ogun.  Wọn goke lọ lati ba awọn Amaleki jà – bawo ni iṣubu wọn ti pọ to!  Awọn ara Amaleki kan naa yii ti wọn ti ṣẹgun pẹlu irọrun lẹẹkan rí nipa iranlọwọ Ọlọkrun, lé wọn sá patapata nisisiyii, wọn si lé wọn sare pada sọdọ Mose, ẹni ti o jokoo ninu Agọ ni ibudo.

**AWỌN IBEERE**

1. Awọn amí wo ni awọn Ọmọ Israẹli gbagbọ́?
2. Ki ni abayọrisi iroyin ti wọn ṣe fun awọn eniyan naa?
3. Ki ni wọn fẹ ṣe?
4. Ki ni idajọ ti Ọlọrun rán si wọn?
5. Ki ni awọn Ọmọ Israẹli fẹ ṣe lẹyin ti wọn gbọ́ idajọ naa?
6. Njẹ Mose ba wọn lọ?
7. Ki ni ṣẹlẹ nigba ti awọn Ọmọ Israẹli ba awọn ara Amaleki jà?